# ỌTUN ÌMỌ̀ NÍNÚ ÌTÀN-ÀRÒSỌ D. O. FÁGÚNWÀ



*Olóòtú:*
**Olúyẹ́misí Adébọ̀wálé**
**Dúró Adélékè**
**Àrìnpé Adéjùmọ̀**

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

A tẹ ìwé yìí jáde láti ilé-iṣẹ́

The Capstone Publications

Gbogbo ẹ̀tọ́ àti àṣẹ lórí rẹ̀ jẹ́ ti

© *Ẹgbẹ́ Onímọ̀-Èdè Yorùbá (Yorùbá Studies Association of Nigeria) 2016*

Ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ da ohunkóhun kọ láti inú ìwé yìí ní ọ̀nàkọnà yàtọ̀ fún ìlò ara tirẹ̀ láìgba àṣẹ fún ṣíṣe bẹ́ẹ̀ láti ọwọ́ Ẹgbẹ́ Onímọ̀-Èdè Yorùbá. A lè ṣe ìwádìí ní:

**The Capstone Publications**
22, Market Street, Shomolu, Lagos
Tel: 08029749341/08072413959

Typesetting by: Temisayo Ventures, Faculty of Arts, U.I.

Printed by: Agoro Publicity Company, Ibadan.

ISBN: 978-34934 – 9 – 3

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

## ÀKÓÓNÚ


*Ojú ìwé*

Àwòrán Olóyè D.O. Fágúnwà iii
Ìtàn ìgbésí ayé Fágúnwà iv
Ìdúpẹ́ v
Ọ̀rọ̀ ìṣáájú vi
Àkóónú vii
Ìfáàrà ix

**ÌṢÍ KÌN-ÍN-NÍ: ÌKỌ́NI, ÌTỌ́NI ÀTI ÌṢẸ̀DÁNÌYÀN**

1. Àbùdá àdámọ́ ìkọ́ni nínú àwọn ìtàn-àròsọ D.O. Fágúnwà 2
2. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti àsọtẹ́lẹ̀ nínú àsọdàsílẹ̀ D.O. Fágúnwà 23
3. Fágúnwà gẹ́gẹ́ bí apanilẹ́rìn-ín òǹkọ̀wé alátinúdá 48
4. Fífi tíọ́rì ìgúnni ní kẹ́sẹ́-inú ẹ̀dáníyàn ti Abraham Maslow yiri ìtàn-àròsọ D.O. Fágúnwà wò 57
5. Ìfẹ̀dáṣẹ̀sín nínú ìtàn-àròsọ Fágúnwà 68
6. The writer as a moralist: A study of Daniel Ọlọrunfẹmi Fagunwa's Ìrèké Oníbùdó 76
7. Realism in D.O. Fágúnwà's Novel: A case study of *Ògbójú Ọdẹ nínú Igbó Irúnmọlẹ̀* 86
8. Ìtagbọ́n-ínú nínú ìwé Fágúnwà 90

**ÌṢÍ KEJÌ: ÀṢÀ, ÈRÒ ÀTI ÌGBÀGBỌ́ YORÙBÁ**

9. Ìhà tí D.O. Fágúnwà kọ sí ìjà àti ìpárí ìjà láwùjọ Yorùbá nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ rẹ̀ 100
10. Ìhà tí Fágúnwà kọ sí ètò ìdájọ́ ní àwùjọ Yorùbá 113
11. Ìfojú àṣà ìfúnnilórúkọ àdàpè wo àwọn orúkọ ẹ̀dá-ìtàn Fágúnwà 119
12. Ìlò orúkọ bí ìfiwàwẹ̀dá nínú *Àdìítú Olódùmarè* 126
13. Socio-semiotic interpretations of gift items given to some characters in Fágúnwà novels: The perspective of Yorùbá cultural beliefs 136
14. Ìṣèwádìí ìmọ̀-ìlò-àmì èrò-ìjìnlẹ̀ àti Ẹ̀sìn-abínibí nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ D. O. Fágúnwà 147
15. Orúkọ Olódùmarè nínú iṣẹ́ Fágúnwà 158
16. The Yorùbá perception of the relationship between the living and the dead: Fágúnwà's novel in cultural perspective 167
17. Ìlò oògùn fún ìdábòbò nínú àwọn ìwé Fágúnwà 179
18. Representations of crime in selected novels of D. O. Fágúnwà 186
19. Àgbéyẹ̀wò àṣà nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ Fágúnwà 196
20. Ìjàjàgbara àṣà Yorùbá nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ D.O. Fágúnwà 208
21. Àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá nínú àwọn ìtàn-àròsọ Fágúnwà: Ẹ̀kọ́ fún orílẹ̀-èdè Nàìjíríà 218
22. Fágúnwà àti ètò ọrọ̀-ajé àwùjọ Nàìjíríà 235
23. Àgbéyẹ̀wò ọ̀rọ̀ ìfẹ̀ àti ìgbeyàwó nínú àṣàyàn ìwé ìtàn-àròsọ Fágúnwà 246


UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

**ÌṢÍ KẸTA: ÌṢỌWỌ́LỌ̀-ÈDÈ ÀTI ỌGBỌ́N ÌSỌ̀TÀN**

24. More understanding of interaction of Yorùbá bare nouns with *kan, náà* and *nìkan*: Evidence from novels of Fágúnwà 262
25. Contextual analysis of focus constructions and content-questions in Fagunwa's *Ògbójú ọdẹ nínú igbó irúnmọlẹ̀* 282
26. Àgbéyẹ̀wò ọnà-èdè nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ D.O. Fágúnwà márààrún 296
27. Ìlò-èdè nínú ọ̀rọ̀ àlàáfíà àti aàwọ̀ nínú ìwé ìtàn-àròsọ Fágúnwà 310
28. Ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ àti ẹ̀dà-ìṣẹ̀lẹ̀ nínú ìwé Fágúnwà, atọ́kùn fún wíwa ọkọ̀ olú ẹ̀dá-ìtàn dé èbúté yíyanjú 319
29. Àgbéyẹ̀wò àwọn ìtàn àròsọ Fágúnwà gẹ́gẹ́ bí àlọ́ 328

**ÌṢÍ KẸRIN: Ọ̀RỌ̀ TAKỌTABO**

30. Fágúnwà gẹ́gẹ́ bíi òǹkọ̀wé aṣẹ̀tọ́fábo 341
31. Àwòrán obìnrin nínú ìwé ìtàn-àròsọ Fágúnwà 350
32. Orogún ṣíṣe nínú àgbékalẹ̀ iṣẹ́ Fágúnwà: Ojú àmúwòye àwùjọ fún ìtúpalẹ̀ kíkún 362
33. Ìwà obìnrin nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ Fágúnwà 375

**Àkójọpọ̀ Orúkọ Àwọn Òǹkọ̀wé** 385

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

## ORÍ KỌKÀNDÍNLỌ́GBỌ̀N

# ÀGBÉYẸ̀WÒ ÀWỌN ÌWÉ ÌTÀN ÀRÒSỌ FÁGÚNWÀ GẸ́GẸ́ BÍ ÀLỌ́

**ÀKÀNGBÉ Clement Adéníyì**

### Ìfáárà

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní "Àjànàkú kọjáa mo rí nǹkan fìrí, bí a bá rí erin ká kúkú sọ pé a rí erin", olóògbé Dáníẹ̀lì Oròwọlé Fágúnwà (1903-1963) kúrò ní ọ̀pìjẹ̀ láàrin òǹkọ̀wé ìtàn àròsọ Yorùbá. Ìtàn àròsọ márùn-ún ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni Fágúnwà kọ: *Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmalẹ̀* (*Ògbójú*) 1938, *Igbó Olódùmarè* (*Igbó*) 1949, *Ìrèké Oníbùdó* (*Ìrèké*) 1949, *Ìrìnkèrindò Nínú Igbó Elégbèje* (*Ìrìnkèrindò*) 1954 àti *Àdììtú Olódùmarè* (*Àdììtú*) 1961. Yàtọ̀ sí àwọn wọ̀nyí, Fágúnwà tún ni àwọn iṣẹ́ mìíràn bí *Ìrìnàjò: Apá Kìíní* (OUP 1963); *Ìtàn Olóyin* (OUP 1964); Fágúnwà, Délànọ̀, I.O. àti àwọn yòókù, *Àṣàyàn Ìtàn* (Nelson 1959); Fágúnwà àti Láṣebìkan, *Ọ̀jọ́ Asọ̀tàn* (Heinemann 1964); tí a tẹ̀ jáde lẹ́yìn ikú rẹ̀. Fágúnwà àti L.J Lewis ni ó jọ kọ *Taíwò àti Kẹ́hìndé Ìwé Kìíní*, (OUP 1948); *Taíwò àti Kẹ́hìndé Ìwé Kejì* (OUP 1950); *Taíwò àti Kẹ́hìndé Ìwé Kẹta* (OUP 1950); àti *Taíwò àti Kẹ́hìndé Ìwé Kẹrin* (OUP 1951). Àwọn ìwé ìtàn àròsọ márààrún tí Fágúnwà kọ ni yóò jẹ wá lógún nínú pépà yìí níbi tí a ó ti fi ojú àlọ́ wo àwọn ìtàn inú ìwé náà.

Abala mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a pín pépà yìí sí. Ìfáárà ni ó ṣíwájú, Àlọ́ Yorùbá, Tíọ́rì Ìtàtarè-iṣẹ́, Àfiwé Iṣẹ́ Fágúnwà àti Àlọ́, àti Ìyapa Iṣẹ́ Fágúnwà sí Àlọ̀ ni ó tẹ̀lé ara wọn. Àgbálọgbábọ̀ ni a fi kádìí ìjíròrò wa.

### Àlọ́ Yorùbá

Àlọ́ jẹ́ ọ̀kan lára lítíréṣọ alohùn Yorùbá. Abẹ́ ewì àrángbọ̀ gan-an ni a to àlọ́ sí, àwọn wọ̀nyí ni a mọ̀ sí alábùdá, tí Ọlátúnjí (1984:8) pè ní "feature types". Gẹ́gẹ́ bí Ọpádọ̀tun (1994:1) ti sọ, "Àlọ́ jẹ́ oríṣi lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá kan tí a máa ń lò fún ìdárayá, ìgbádùn àti ìkọ́ni-lẹ́kọ̀ọ́" Àlọ́ pín sí oríṣìí méjì; àpamọ̀ àti àpagbè. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pe àlọ́ àpamọ̀ ni ó máa ń ṣe atọ́kùn fún àlọ́ àpagbè torí pé a máa fi ń ṣíde ni, iṣẹ́ tí àlọ́ àpamọ̀ ń ṣe ju ti atọ́nà lásán yìí lọ torí pé àdìtú gbáà ni èdè rẹ̀. Ní ti èrò Ọpádọ̀tun, "wọ́n máa ń lo àlọ́ àpamọ̀ gẹ́gẹ́ bí ìfáárà fún àlọ́ onítàn. Wọ́n máa ń lò ó fún pípalẹ̀ ọkàn àwọn olùgbálọ̀ọ̀ mọ́ sílẹ̀ de àlọ́ onítàn. Wọ́n tún máa ń lò ó títí tí àwọn ẹgbẹ́ alálọ̀ọ́ kan yóò fi ṣa ojú jọ tán" (1994:1). Èyí fi hàn pé iṣẹ́ ìṣíde ni àlọ́ àpamọ̀ wà fún. Bí iṣẹ́ ìṣíde rẹ̀ tilẹ̀ tò ó sí ipò yẹpẹrẹ, àtàrí àjànàkú ni èdè rẹ̀, èyí tí kì í ṣe ẹrù fún ọmọdé. Ìhun rẹ̀ pẹ̀lú fakíki, àsúnkì ẹ̀kọ́ ìjìnlẹ̀ ni, ó sì ń ṣe àfihàn èrò Yorùbá nípa àyíká wọn. Ǹ jẹ́ bí àlọ́ àpamọ̀ tí ó jẹ́ akéde lásán fún àlọ́ àpagbè bá le tẹ̀wọ̀n báyìí pẹ̀lú ìwúlò tí ó ga, a kò ṣàìmọ̀ pé láàríjà ti àlọ́ àpagbè yóò gadabú!

Oríṣìí kejì ni àlọ́ àpagbè èyí tí Ògúndèjì (1991:26) pè ní àlọ́ onítàn. Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe sọ, "àlọ́ onítàn yìí náà ni a mọ̀ sí àlọ́-àpagbè, papàá jùlọ láàrin àwọn Ọyọ́ Yorùbà". Ní ti Ọpádọ̀tun,

> Àlọ̀ onítàn ni ìtàn alohùn tí kì í ṣe òótọ́ ṣùgbọ́n tí ó dá lórí ènìyàn tàbí ẹranko tàbí ẹyẹ tàbi iwin tí a sọ láti kọ́ ọmọdé ní ẹ̀kọ́ tàbí láti fi ìdí abájọ kan múlẹ̀. Irú àlọ̀ bẹ̀ẹ̀ lè ní orin tí

yóò ní ègbè, ó sì lè ṣàì nì orin dé ibi pé yóò ní ègbè."
(1994:1)

A fi ara mọ́ èrò Ògúndèjì àti Ọpádọ̀tun pé ó sàn kí a lo àlọ́ onítàn dípò àlọ́ àpagbè nítorí pé àlọ́ onítàn kẹnú ó sì gbòòrò ju àlọ́ àpagbè lọ. Fún ìdí èyí, àlọ́ onítàn ni a ó ṣe àmúlò nínú iṣẹ́ yìí.

Àlọ́ onítàn jẹ́ ọ̀nà tí Yorùbá máa ń gbà láti kọ́ àwọn ọmọdé ní ẹ̀kọ́, èyí ni Yorùbá ṣe máa ń sọ pé àlọ́ ni tọmọdé, òwe ni tàwọn àgbà. Ó jẹ́ ọ̀nà ìmútànlò láti fi ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn bẹ́ẹ̀ kọ́ àwọn ọmọdé lọ́gbọ́n. Ìjàpá tìrókò ọkọ Yánníbo, ọlọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́, ni ó sábà máa ń jẹ́ olú ìtàn àlọ́ Yorùbá. Nínú ìṣesí rẹ̀, a máa fi ọgbọ́n àlùmọ̀kọ́rọ́yí rẹ̀ dé àwọn ẹ̀dá ìtàn yókù mọ́lẹ̀ ṣùgbọ́n, ìkà a máa ka oníkà, ìṣu ìkà rẹ̀ a máa ta fún un jẹ, a sì máa ti ipa bẹ́ẹ̀ gba ìjìyà tí ó tọ́. Kò sí ìṣe ènìyàn kan tí àwọn ẹ̀dá ìtàn wọ̀nyí kìí ṣe. Àmọ́ sábàbí gbogbo ìwọ̀nyí ni láti kọ́ ọmọdé ní ẹ̀kọ́ nípa bí à á ṣe hùwà ní àwùjọ. Apààlọ́ ni ó máa ń pa àlọ́, àwọn ọmọdé ni ó sì dúró bí olùgbọ́. Apààlọ́ ni ó máa ń ti ipasẹ̀ àlọ́ rẹ̀ wáásù fún àwọn ọmọdé nípa fífi ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìṣẹ̀lẹ̀ inú àlọ́ rẹ̀ ṣe kìlọ̀kìlọ̀ ìwà nípa sùúrù, ìtẹ́ríba, ìforítì, ìtẹpámọ́ṣẹ́, ìṣòtítọ́, ìkááánú, ìrànlọ́wọ́, ìfẹ́, ìpamọ́ra, ìṣoore, abbl.

## Àgbékalẹ̀ Àlọ́

Àlọ́ onítàn Yorùbá ní ètò gúnmọ́ tí ó máa ń tẹ̀lé. Ìfáárà ni ó máa ń bẹ̀rẹ̀ àlọ́ onítàn, èyí ni Ògúndèjì (1991:26) pè ní ìsọ̀rọ̀ngbèsì kékeré láàrin apàlọ́ àti olùgbọ́. Àpalọ̀ ni àgbàlagbà tí ó ń pa àlọ́, àwọn ọmọdé tí ó ń tẹ́tí sí apàlọ́ yìí ni olùgbọ́.

| | | |
|---|---|---|
| Àpẹẹrẹ nìyí: | *Apààlọ́*: | Àlọ́ o |
| | *Olùgbọ́*: | Ààlọ̀ |
| | *Apààlọ́*: | Àlọ́ mi dá fùrùgbagbòó |
| | *Olùgbọ́*: | Kó má gbé àgbo ọmọ mi lọ |
| | *Apààlọ́*: | Àlọ́ mi dá lórí Ìjàpá tìrókò ọkọ Yańníbo àti Ìyá Ẹlẹ́pà. |

Oríṣìíríṣìí ni ìfáárà yìí jẹ́, ó sì yàtọ̀ díẹ̀díẹ̀ láti àdúgbò kan sí òmíràn.

Àjọṣepọ̀ a máa wáyè láàrin àwọn ohun abẹ̀mí àti aláìlẹ́mìí nínú àlọ́ onítàn. Apàlọ́ a máa dá onírúurú ọgbọ́n láti mú ìtàn rẹ̀ dùn kí àwọn olùgbọ́ rẹ̀ sì gbádùn rẹ̀. A máa lo èdè àwàdà àti ọ̀rọ̀ tí ó panílẹ́rìn-ín, a máa ṣe ìsínjẹ àwọn ẹ̀dá ìtàn bí i kí ó máa ránmú sọ̀rọ̀ láti sín ìjàpá jẹ. Bákan náà ni apàlọ́ máa ń fi orin bọ àlọ́ láàrin, èyí sì máa ń jẹ́ orísun ìdárayá gbáà. Àwọn ọmọdé a máa gbe orin yìí, wọn a máa pàtẹ́wọ́ sí i, wọn a máa lùlù sí i, wọn a sì máa jó sí i pẹ̀lú.

Láàríjà àlọ́ onítàn ni ìdánílẹ́kọ̀ọ́ ìwà. Yorùbá ṣe àgbékalẹ̀ àlọ́ láti dá àwọn ọmọdé lẹ́kọ̀ọ́ nípa ìwà ọmọlúàbí, láti mọ rere yàtọ̀ sí ibi àti láti ṣe àfihàn àwùjọ Yorùbá fún wọn. Ìdí nìyí tó fi jẹ́ pé ní ìparí àlọ́, apàlọ́ a máa ṣe àfàyọ ẹ̀kọ́ tí àlọ́ yẹn kọ́ wa. Bí àpẹẹrẹ: Ìtàn yìí kọ́ wa pé kí á má máa jalè, ìtàn yìí kọ́ wa pé kí á má máa ṣe ojúkòkòrò, ìtàn yìí kọ́ wa pé kí á má máa hu ìwà ìkà, abbl. Gẹ́gẹ́ bí Ògúndèjì ti wòye, "nígbà míràn nípàrí ìtàn bẹ́ẹ̀ apàlọ́ le pe àkíyèsí sí ìdí abájọ tí ó súyọ nínú ìtàn" (1991:27). Ìdí abájọ bẹ́ẹ̀ le jẹ́ ìdí tí ẹyẹ àkókó ṣe ń fi ẹnu sọ igi kiri, ìdí tí ẹlẹ́dẹ̀ ṣe ń fi imú túlẹ̀ kiri, ìdí tí ẹ̀yìn ìjàpá fi rí kángun kàngun, abbl.

Ìgúnlẹ̀ ni ó máa ń tẹ̀lé àfihàn ẹ̀kọ́ inú àlọ́, òun náà sì ni ìgbésẹ̀ tí ó gbẹ̀yìn nínú àlọ́ pípa. Ìgúnlẹ̀ àlọ́, gẹ́gẹ́ bí ìfáárà, máa ń yàtọ̀ láti àdúgbò dé àdúgbò. Bí àpẹẹrẹ:

*Apààlọ̀:* Ìdí àlọ́ mi rè é gbáńgbáláká



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Ìdí àlọ́ mi rè é gbàǹgbàlàkà
Kó gborógbó jẹ kó má ṣe gbobì jẹ
Nítorí orógbó ní í gbóni sáyé
Obì ní í gbó wọn sọ́run
Bí mo bá purọ́
Kí agogo ẹnu mi kó má dún lẹ́ẹ̀mẹta
Ṣùgbọ́n bí n kò bá purọ́
Kí agogo ẹnu mi dún lẹ́ẹ̀mẹta
Ó di pó
Ó di pó
Ó di pó
Ó ró nbí ò ró

*Olùgbọ́:* Ó ró bàbá (Ògúndèjì, 1991:27).

Àpẹẹrẹ mìíràn nìyí: Ìdí àlọ́ mi rèé gbáńgbáláká
Ìdí àlọ́ mi rèé gbàǹgbàlàkà
Bí mo bá parọ́
Kẹ́gùn-ún ọ̀gẹ̀dẹ̀ gún mi lẹ́sẹ̀
Kó má mà yọ
Kí n tẹ̀bà
Kí n sì rọ́bẹ̀ jẹ é
Kígba ọmọ ó gbé mi sin. (Ọ̀pádọ̀tun, 1994:7).

Kókó-ọ̀rọ̀ ṣe pàtàkì nínú àlọ́. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣíwájú, ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìwà ni olúborí kókó-ọ̀rọ̀ àlọ́ onítàn. Ṣé ìṣàlùwàlà ológbò, ọgbọ́n àtikẹ́ranjẹ ni. Gbogbo àfojúsùn apàlọ́ ni láti kọ́ àwọn ọmọdé ní ẹ̀kọ́. Apàlọ́, a máa yọ̀nbó ìwà ọmọlúàbí bí i sísọ òtítọ́, ṣíṣe ìrànlọ́wọ́ fún ẹnìkejì, níní ìfẹ́, títẹpámọ́ṣẹ́, síṣe àánú, níní ìfaradà, abbl.; a sì máa bu ẹnu àtẹ́ lu síṣe ọ̀lẹ, síṣe ìmẹ́lẹ́, níní ọ̀kánjúwà, síṣe ojúkòkòrò, síṣe òfófó, olè jíjà, irọ́ pípa, ilẹ̀ dídà, inú bíbí, ìkà ṣíṣe, ìkòríra, owú jíjẹ, gbígbéraga, hìhàwọ́, abbl. Àwọn kókó-ọ̀rọ̀ amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ tàbí àsọmọgbè tí a fi máa ń gbé ẹ̀kọ́ ìwà kalẹ̀ ni ẹ̀san, ìjà orogún, àti ìdánwò. Ìdí-abájọ ni kókó mìíràn tí àlọ́ onítàn máa ń dá lé lórí.

Ìhun ìtàn àlọ́ onítàn jẹ́ èyí tí ó lọ tààrà, tí kò rújú, tí kò sì fa pọ́n-ọ́n-na. Àgbékalẹ̀ àlọ́ kò dàbí ti ìtàn àròsọ tàbí eré onítàn tí ó ní ìbẹ̀rẹ̀ nínú èyí tí a ti ń ṣe àfihàn àwọn ẹ̀dá ìtàn; lẹ́yìn èyí tí a ó bẹ̀rẹ̀ sí rí ìfarakínra àti ìkọlura àwọn ẹ̀dá ìtàn, èyí tí yóò bí rúkèrúdò, kí ó tó wá dé ìkòríta yíyanjú nínú èyí tí oníkálùkù ẹ̀dá ìtàn yóò ti gba ìdájọ́ tí ó tọ́ sí i. Àwọn àbùdá tí ó hànde nínú ìhun àlọ́ Yorùbá ni àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀, ìṣẹ̀lẹ̀ àyísódì àti àyípadà ìgbà (Ògúndèjì, 1991 : 33-36).

Àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ jẹ́ àbùdá bárakú fún òpó àlọ́ onítàn Yorùbá nínú èyí tí ìṣẹ̀lẹ̀ kan náà yóò máa wáyé léraléra. Irúfẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ a sì máa ní àyọrísí kan náà ní gbogbo ìgbà kí ó tó wá di pé yóò ní àyọrísí tí ó yàtọ̀ ní ìgbẹ̀yin-gbẹ́yín. Àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ a máa mú kí ìtàn gùn. Irúfẹ́ àlọ́ onítàn báyìí a sì máa jẹ́ àpagbè nínú èyí tí orin, ìlù àti ijó sodo sí. Àpẹẹrẹ ni àlọ́ Ìjàpá àti Ìyá ẹlẹ́pà, òmíràn ni Ìjàpá àti Ìyá alákàrà. Nínú àlọ́ Ìjàpá àti Ìyá alákàrà ni Ìjàpá àti ọmọ rẹ̀ ti máa ń dá ọmọ alákàrà lọ́nà tí ó bá ń kiri ọjà rẹ̀ lọ sí abúlé keji. Ìjàpá àti ọmọ rẹ̀ yóò fi ewé ọ̀gẹ̀dẹ̀ gbígbẹ bo ara, wọn yóò sì bẹ́ sọ́nà lójijì bí i àǹjọ̀nnú láti



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

dẹ́rù bá ọmọ alákàrà. Ìbẹ̀rùbojo ni ìyẹn yóò fi da ọjà rẹ̀ nù tí yóò sì sá àsálà fún ẹ̀mí rẹ̀. Ìjàpá àti ọmọ rẹ̀ ṣe báyìí fún ìgbà pípẹ́ kí ọwọ́ Ọsanyìn ẹlẹ́sẹ̀ kan tó bà á.

Ìṣẹ̀lẹ̀ àyísódì a máa wáyé nígbà tí àyọrísí ìgbésẹ̀ tí ẹ̀dá ìtàn kan bá gbé ní àkọ́kọ́ bá ní àyọrísí tí ó yàtọ̀ sí ti àkọ́kọ́ ìgbà tí ẹ̀dá ìtàn yẹn tàbí ẹ̀dá ìtàn mìíràn bá gbé irú ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Ògúndèjì,

> Ìṣẹ̀lẹ̀ àyísódì máa ń wáyé nínú àlọ́ onítàn nígbà tí àyọrísí ìgbésẹ̀ tí ẹ̀dá ìtàn kan gbé bá jẹ́ àyísódì tàbí òdìkejì àyọrísì irú ìgbésẹ̀ kan náà tí ẹ̀dá ìtàn mìíràn tàbí ẹ̀dá ìtàn kan náà yẹn tí kọ́kọ́ gbé. (1991:34).

Àpẹẹrẹ èyí wọ́pọ̀ nínú ìtàn olórogún nínú èyí tí ìyàwó yóò ti ṣe oríire tí yóò sì bun ìyáálé nínú rẹ̀, àmọ́ èyí kò ní tẹ́ ìyáálé lọ́rùn, òun náà yóò sì fẹ́ gbé irú ìgbésẹ̀ tí ìyàwó gbé àmọ́ dípò oríire, ìfòòró àti ìdààmú ni yóò bá pàdé torí pé òun kò ní le ní irú sùúrù àti ìfaradà tí ìyàwó ní. Ìṣẹ̀lẹ̀ àyísódì yìí a máa pín ìtàn sí abala méjì ọgbọọgba nínú èyí tí ire àti ibi yóò ti fojú hàn. Àyípadà ìgbà ni àbùdá kẹta tí ó hànde nínú àlọ́ onítàn. Èyí máa ń wáyé nígbà tí ẹ̀dá ìtàn kan tí ó là tí ó lu ní ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn bá wá di akúṣẹ̀ẹ́ àti atọrọjẹ ní ìparí ìtàn. Ẹni tí ó ṣe aláìní ní ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn sì le wá di ọlọ́rọ̀ ní ìparí ìtàn.

Ìṣẹ̀lẹ̀ àlọ́ onítań kò bọ̀wọ̀ fún àkókò rárá, bẹ́ẹ̀ sì ni kò bọ̀wọ̀ fún ibùdó pẹ̀lú. Ìṣẹ̀lẹ̀ àlọ́ le wáyé ní ayé ó sì le ṣẹlẹ̀ ní alède ọ̀run. Ọsán àti òru kò ṣe ìdíwọ́ kankan fún ìṣẹ̀lẹ̀ àlọ́, ọgbọọgba ni ọ̀sán àti òru jẹ́. Ẹwẹ̀, kò sí ààlà láàrin alààyè àti òkú, wọn á jọ máa bá ara wọn ṣe. Bẹ́ẹ̀ ni ọ̀run kò jìnnà sí ayé, ará ayé le tara lọ sí ọ̀run kí ó sì padà wéré, bẹ́ẹ̀ ni ará ọ̀run náà le dá kán wá sáyé kí ó sì tún padà. Irúfẹ́ ìhà tí àlọ́ onítàn kọ sí ibùdó ìṣẹ̀lẹ̀ àti àkókò ìṣẹ̀lẹ̀ yìí a máa jẹ́ kí ìṣẹ̀lẹ̀ mérìíyìírí rọrùn láti ṣẹlẹ̀. Ìfiwàwẹ̀dá yìí tún bọ̀ mú kí àbùdá mérìíyìírí ta ẹkàn mọ́lẹ̀ dáadáa nínú àlọ́.

Nípa ìlò èdè, yàtọ̀ sí àwọn gbólòhùn ìṣíde àti ìkádìí tí a ti sọ̀rọ̀ bá, ìlò èdè àlọ́ rọrùn. Èdè ojoojúmọ́, èdè tí kò farasin ni a máa ń bá nínú àlọ́ onítàn nítorí pé àwọn èwe, àwọn ìpẹ̀ẹ̀rẹ̀ ni olùgbọ́ àlọ́. Fún ìdí èyí, gbólòhùn kékèké, gbólòhùn tààrà, àti èdè tí ó rọrùn fún ọmọdé láti mọ̀ ni apààlọ́ máa ń yàn láàyò. Òwe, ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀, àkànlò èdè, àti èdè ìkàsì kò wọ́pọ̀ nínú àlọ́. Àwọn àbùdá tí a ti ṣàlàyé wọ̀nyí ni ó jẹ́ bárakú fún àgbékalẹ̀ àlọ́ onítàn Yorùbá.

## Àwọn Olú Ẹ̀dá Ìtàn Fágúnwà

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ìwé ìtàn àròsọ rẹ̀ máràárún yàtọ̀ sí ara wọn, síbẹ̀ àbùdá tí ó hànde nínú òpó ìtàn rẹ̀ ni ṣíṣe àgbékalẹ̀ olórí ẹ̀dá ìtàn gẹ́gẹ́ bí àkọni, arẹwà, ọlọgbọ́n, olóògùn àti aláṣeyọrí, ó jẹ́ àkàndá ẹ̀dá tí yóò ṣetán láti fi ẹ̀mí rẹ̀ la ewu nínú ìrìnàjò láti mú ìdàgbàsókè bá ìlú rẹ̀. Èyí lè jẹ́ láti lọ gba nǹkan pàtàkì tí yóò fún Ọba ìlú wọn ní àlàáfíà àti aásìkí láti ọ̀dọ̀ ọba ìlú Òkè Láńgbòdó (*Ògbójú*), ìrìnàjò lọ sí ìlú ìtànforítì láti lọ gba nǹkan tí ọba ìlú Àlúpàyídà yóò lò fún àìsàn rẹ̀ wá (*Ìrèké*), tàbí lílọ sí Òkè Ìrònú láti lọ ká èso igi ìrònú wá fún ọba ìlú wọn (*Ìrìnkèrindò*). Olú ẹ̀dá ìtàn yìí kì í dá nìkan lọ sí ìrìnàjò bẹ́ẹ̀, a máa ní ìsọmọgbè àti olùrànlọ́wọ́. Ìsọmọgbè wọ̀nyí le jẹ́ àwọn ògbójú ọdẹ bí Kàkó, Ìmọ̀dòye, Olóhùn-iyọ̀, Elégbèdè ọdẹ, Èfọ̀iyẹ́ àti Àràmọ̀ndà Ọkùnrin (*Ògbójú*); alágbára àti ọ̀jọ̀gbọ́n bí i Èròọkàn àti Kùmọ́fẹ̀hìntì (*Ìrèké*); tàbí onírúurú ẹ̀dá pàtàkì bí Aiyédèrù-ẹ̀dá, Inúlaiyéwà, Ewé-ẹiyẹ (babaláwo), Olójúmájẹ̀lẹ́, Kùmọ́dìran, Fìlàsaiyépọ̀, Ìbẹ̀mbẹ́ Ọlọ́kùnrùn, àti Ìrèké (oníférè) (*Ìrìnkèrindò*).

Nínú ìrìnàjò yìí, olú-ẹ̀dá ìtàn a máa kojú ìṣòrò àti wàhálà, ọ̀pọ̀ nínú àwọn ìsọmọgbè rẹ̀ lè jásẹ̀ látàrí ìyọnu wọ̀nyí àmọ́ nínú òfìì òun ọ̀láà, ọmọ pándọ̀rọ̀ tirẹ̀ a máa

gbó. Bí ìṣòro yìí bá tilẹ̀ fẹ́ kọjá agbára olú ẹ̀dá ìtàn yìí, ìrànlọ́wọ́ a máa wá ní oríṣìí ọ̀nà yálà kí baba tàbí ìyá rẹ̀ tí ó ti di olóògbé yọ sí i láti ràn án lọ́wọ́, tàbí arẹwà obìnrin bí Ìrànlọ́wọ́ (*Ògbójú*) àti Ìfẹ́pàtàkì (*Ìrèké*). Ní igbẹ̀yìn, ọwọ́ rẹ̀ yóò tẹ ohun tí ó wá lọ sí ìrìnàjò, yóò sì padà sílé pẹ̀lú ayọ̀. A máa ti ipasẹ̀ àṣeyọrí yìí di ọlọ́lá àti ọlọ́rọ̀, kódà a máa jọba pẹ̀lú gẹ́gẹ́ bí ìmọyì akitiyan òun làálàá rẹ̀ láti ọ̀dọ̀ àwọn ará ìlú. Ní èdè kan, aláìlọ́bọ̀ ni olú ẹ̀dá ìtan wọ̀nyí máa ń jẹ́ nínú ìrìnàjò wọn.

Láìṣe àníàní, abílọ́jẹ̀ ni Fágúnwà nínú àṣà àti ìṣe Yorùbá. Fún ìdí èyí, kò yani lẹ́nu pé ó fi ìlànà àlọ́ ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìtàn àròsọ rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí awo nínú lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, ó fi ìmọ̀ àbáláyé rẹ̀ dá omi lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ láti polongo ìmọ̀ àbáláyé yìí kí ó sì ti ipa bẹ́ẹ̀ gbé ìmọ̀ ọ̀tun jáde. Ní ṣíṣe èyí, Fágúnwà kì í ṣàdéédé gbé lítíréṣọ̀ alohùn wọ inú férémù ti àpilẹ̀kọ lọ́bọ̀rọ́ ṣùgbọ́n a máa ṣe àmúlò rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí èròjà àdídùn iṣẹ́ àtinúdá rẹ̀ kí ògo àti ète iṣẹ́ àtinúdá bẹ́ẹ̀ le múnádóko dáradára. Láárijà èyí ni pé irú ọgbọ́n yìí a máa mú kí iṣẹ́ òǹkọ̀wé jẹ́ iṣẹ́ tí ó yẹ kí ó jẹ́ fún àwùjọ, ìdí nìyí tí Fágúnwà ṣe lo àlọ́ bí fèrè láti polongo iṣẹ́ rẹ̀ fún ọmọ aráyé. Ìrèlè (1975:79) náà jẹ́rìí sí èyí pé:

> ...his narrative technique flows directly out of the oral traditional; at the same time, it is evident that he strove, even with noticeable strain, to get beyond the limitations of the tradition in the context of an extended literary medium.

Ìtọ́kasí yìí fi ẹ̀rí hàn pé òǹkọ̀wé kàn lo àlọ́ bí gbohùngbohùn fún iṣẹ́ rẹ̀ ni, iṣẹ́ rẹ̀ lóòrìn ju àlọ́ lọ.

Lóòótọ́, àlọ́ hànde púpọ̀ nínú iṣẹ́ Fágúnwà àmọ́ ó ṣe pàtàkì látí yán an pé àlọ́ nìkan kọ́ ni orísun iṣẹ́ wọ̀nyí. Ọ̀pọ̀ iṣẹ́ ni òǹkọ̀wé tàtarè sínú ìtàn rẹ̀ kí ó le ládùn kí ó sì lóyin. Àwọn oríṣìí ọ̀nà mẹ́ta gbòógì tí Fágúnwà ti ṣe àfàyọ (èròjà) ni lítíréṣọ̀ ilẹ̀ Gíríkì agbógoyọ, lítíréṣọ̀ Gẹ̀ẹ́sì àti nínú ìtàn àlọ́ ilẹ̀ àwọn Árábù (Adéléké, 2011:32). Àmọ́ ṣé ohun tí ó bá wuni ní pọ̀ lọ́rọ̀ ẹni, ọ̀rọ̀ àlọ́ ni ó jẹ wá lógún, òun ni a ó sì ṣe àgbéyẹ̀wò fínnífínní nínú iṣẹ́ yìí.

**Tíọ́rì ìtàtarè-iṣẹ́ láti inú iṣẹ́ kan sí òmíràn**

Tíọ́rì Ìtàtarè-iṣẹ́ láti inú iṣẹ́ kan sí òmíràn tí a mọ̀ sí "Intertextuality" jẹ́ èyí tí Julia Kristeva, ọmọ ilẹ̀ Faransé tíí ṣe onímọ̀ nípa ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè, gbé kalẹ̀ ní ọdún 1966. Julia Kristeva fi ìdí èrò rẹ̀ múlẹ̀ pé kò sí iṣẹ́ lítíréṣọ̀ kan tí ó dá wà gédéńgbé fúnra rẹ̀ àti pé iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan ni ó kún fún oríṣìíríṣìí àwọn iṣẹ́ mìíràn. Òtítọ́ ọ̀rọ̀ tí kò ṣeé jà níyàn ni pé ṣe ni àkóónú gbogbo iṣẹ́ lítíréṣọ̀ alátinúdá kọ́ ara wọn bí ẹ̀wọ̀n, tí wọ́n sì wọ inú ara wọn bí ẹran tíí wọ inú egungun. Ìdí abájọ sì ni pé gbogbo iṣẹ́ tí ó ti wà ṣaájú ni ó máa ń nípa lórí èrò àti ọgbọ́n àtinúdá òǹkọ̀wé tí ó kọ iṣẹ́ tuntun jáde. Òǹkọ̀wé lè mọ̀ọ́nmọ̀ ṣe àmúlo àwọn abala kan láti inú àwọn iṣẹ́ ti ìṣaájú, ó sì le ṣèèṣì mú wọn lò láìjẹ́ pé ó tilẹ̀ fura rárá. Gẹ́gẹ́ bí ìwòye Hofele (1997:69) nínú Adéléké (2011:10), "Ní kúkúrú èdè, ó ṣe é ṣe kí àwọn ẹdá ìtàn àti òǹsọ̀tàn farahàn ní oríṣìíríṣìí ọ̀nà ẹ̀rẹ̀ọ tí a ti dìídì potóbo kalẹ̀ lọ́nà tí ìdámọ̀ rẹ̀ yóò fi yapá sí ìrísí tàbí ìṣẹ̀dá ìpìlẹ̀ rẹ̀". Adéjùmọ̀ (2011:209) náà fi ara mọ́ èrò yìí. Ó gbà pé àjọṣepọ̀ tí ó jinlẹ̀ wà láàrin lítíréṣọ̀ alohùn àti àpilẹ̀kọ nítorí àwọn méjèèjì jọ máa ń fi ọ̀tún àti òsì wẹ ara wọn ni. Gẹ́gẹ́ bí ó ti wí, "there is inter-relationship between the oral and the written traditions because they constantly nourish each other".

Gẹ́gẹ́ bí èrò Umberto Eco nínú Haberer (2007:57),



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

It is not true that works are created by their authors. Works are created by works, texts are created by texts, all together they speak to each other independently of the intentions of their authors.

Kì í ṣe òtítọ́ pé àwọn òǹkọ̀wé ni ó ń ṣẹ̀dá àwọn iṣẹ́ wọn. Àwọn iṣẹ́ ló ń ṣẹ̀dá iṣẹ́, ìwé ló ń ṣẹ̀dá ìwé, wọn a sì máa fọhùn síra wọn lápapọ̀ yàtọ̀ sí èròngbà ti òǹkọ̀wé.

Èrò Eco yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àjáso àti àjárọ̀ ìrírí òun ọgbọ́n tí òǹkọ̀wé ti ní láti inú àwọn onírúurú ìwé tí ó ti kà àti àwọn ìmọ̀ lọ́kan-ò-jọ̀kan tí ó ti ní ṣẹ́yìn ni ó máa ń paradà di ìwé gẹ́gẹ́ bí iṣu tií paradà di iyán tí àgbàdo sìí paradà di ẹ̀kọ yangan. Àmọ́ ṣá o, ìmọ̀ àti ọgbọ́n inú ìwé nìkan kọ́ ni òǹkọ̀wé máa ń tàtàrè sí inú iṣẹ́ tuntun o, gẹ́gẹ́ bí Eliot nàá ṣe sọ nínú Haberer (2007:61),

(Intertextuality is) a text's dependence on prior words, concepts, connotations, codes, conventions, unconscious practices, and texts. Every text is an intertext that borrow, knowingly or not, from the immense archive of previous culture.

Ìtàtarè-iṣẹ́ jẹ́ ìgbáralé iṣẹ́ kan lórí àwọn ọ̀rọ̀ àsọtì, àbá, ìjású, àmì, àṣà, ìṣe bárakú, àti àkọ́ọ́lẹ̀. Gbogbo ìwé ló jẹ́ àkójọ ìwé tí a yá láti inú ibú àká àṣà, yálà a mọ̀ọ́nmọ̀ tàbí a kò mọ̀.

Ọ̀rọ̀ Eliot yìí ló ṣe ẹ̀rí ọ̀rọ̀ pé kò sí ààlà kan pàtó sí orísun ìmọ̀ tí òǹkọ̀wé lè fi tàtarè. Ó le jẹ́ láti ara ìmọ̀ tí ó bù mu nínú àṣà àti ìṣe, ìtàn, orin, ewì, ààlọ́, ẹ̀sìn, ọ̀ṣèlú, okòwò, abbl.

Adéléke (2011:19 - 34) fi ìdí ọ̀rọ̀ múlẹ̀ pé ìtàtarè-iṣẹ́ pinmirin sínú awọn ìwé Fágúwà, bí ó ti kún inú àwọn ìwé ìtàn àròsọ rẹ̀ máràárùn náà ni ó farahàn púpọ̀ nínú àwọn iṣẹ́ rẹ̀ yòókù. Bí ó ti jẹyọ nínú *Taiwo àti Kẹ́hìndé (ìwé kìnínní sí ìkẹrin)* náà ni ó hànde nínú *Ọ̀jọ́ Asọ̀tàn* ati *Ìtàn Olóyin*. Adéléke tọ́ka sí orísìí ọ̀nà mẹ́ta tí ìtàtarè-iṣẹ́ fi wáyé nínú àwọn ìwé ìtàn àròsọ Fágúnwà. Àwọn ọ̀nà wọ̀nyí ni ìtàtarè lítíréṣọ̀ alohùn sínú iṣẹ́ lítíréṣọ̀ apilẹ̀kọ, títàtarè iṣẹ́ inú ìwé kan sí òmíràn, àti títàtarè bátànì iṣẹ́ àpilẹ̀kọ ilẹ̀ òkèèrè.

**Àfiwé Iṣẹ́ Fágúnwà àti Àlọ́**

Kò sí ọ̀kan nínú àwọn ìwé Fágúnwà tí àmúlò àwọn àbùdá àlọ́ wọ̀nyí kò ti jẹyọ. Orísìí ọ̀nà tilẹ̀ ni èyí gbà wáyé. A rí ibi tí Fágúnwà ti gbé odidi àlọ́ bọ inú ìtàn rẹ̀, èyí sì wáyé lọ́nà tí ó jẹ́ pé gedegbe ni irú àlọ́ bẹ́ẹ̀ hàn sí òǹkàwé. Bí àpẹẹrẹ, ìtàn Àjàǹtálá nínú *Ògbójú* jẹ́ èyí tí kò farasin rárá. Yorùbá a máa sọ ìtán abàmì ọmọ tí ó ti bẹ̀rẹ̀ sí ṣe ìṣe àgbà ní kété tí wọ́n bí i tán. Jàǹdùkú àti onijàgídíjàgan ọmọ ni. Ó ti kékeré ya pòkíì. Ìgbà tí wàhálà rẹ̀ sú àwọn ará ìlú ni wọ́n pa ìmọ̀ pọ̀ láti dọ́gbọ́n mú un jáde ní ìlú, wọ́n sì kẹ́ ẹ sílẹ̀ nínú aginjù. Kín ni ó dé inú aginjù sí, pákáleke rẹ̀ kò jẹ́ kí àwọn ẹranko gbádùn, ó sì fi ìyọnu rẹ̀ tú agbo wọn ká. Yàtọ̀ fún èyí, ìtàn Ológbò ìjàkadì àti ẹkùn (*Ìrèke*) pàápàá jẹ́ àfàyọ láti inú àlọ́. Àlọ́ yìí ṣe àfihàn bí ìjàpá ṣe fi ọgbọ́n tan ọ̀ni pe olóòlà ni òun, òun sì ṣetán láti kọ



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

àwọn ọmọ rẹ̀ ní ilà kí wọ́n baà lè ní àníkún ẹwà. Inú ọ̀ni dùn, ó sì fi gbogbo ara gbà pé kí ìjàpá kọ àwọn ọmọ òun ní ilà. Àmọ́ sí ìyàlẹ́nu, níṣe ni ìjàpá bẹ̀rẹ̀ sí ní pa àwọn ọmọ ọ̀ni ní ọ̀kọ̀ọ̀kan tí ó sì ń fi wọ́n jẹ iyán. Ọmọ kan ṣoṣo tí ó tí kọ ní ilà ni ó bẹ̀rẹ̀ sí ní fi han ọ̀ni láti òkèèrè ní ojoojúmọ́. Ìgbà tí ó sì ṣetán àtilọ, ó tun pa àbíkẹ́yìn ọ̀ni yìí náà, ó sì fi ẹsẹ̀ fẹ́ ẹ. Àmúlò àwọn àlọ́ wọ̀nyí ní odidi ṣègbè ọ̀rọ̀ wa pé Fágúnwà fi àlọ́ ṣe àtẹ̀gùn àwọn ìtàn àròsọ rẹ̀. Ìtàtare-iṣẹ́ ni èyí jẹ́, èyí sì jẹ́ àpẹẹrẹ ìtàtarè lítíréṣọ̀ alohùn sínú iṣẹ́ lítíréṣọ̀ apilẹ̀kọ.

Àkíyèsí kíkún nípa àwọn kókó tí a máa ń rí tọ́ka sí nínú ìtàn Fágúnwà kò fi ibì kan yàtọ̀ sí ti àlọ́ èyí tí ó fihàn pé ìjọra wà láàrin wọn. Bí àpẹẹrẹ, ọ̀pọ̀ àlọ́ a máa dá lérí bí ìjàpá ṣe kojú ìṣòro àti ọgbọ́n tí ó ta láti yọ kúrò nínú ìṣòro yìí. Ìgbà mìíràn, ó le kùnà nínú ìṣòro náà kí ó ṣubú. Olú ẹ̀dá ìtàn Fágúnwà náà lè kó sí tàkúté ọ̀tá, kí o sì ti ipa èyí bọ́ sínú ìṣòro. Kódà irú ìṣoro bẹ́ẹ̀ le ju agbára rẹ̀ lọ kí ó sì jẹ́ pé ọ̀tọ̀ ni ibi tí ìrànlọ́wọ́ rẹ̀ yóò ti wá. Nínú *Ìrèké*, Àrògìdìgbà fi ojú Ìrèké Onídùdó rí màbo. Ìdánwò mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni ó gbé kò ó láyà. Ó ní kí ó kọ́ ilé pẹ̀tẹ́ẹ̀sì ní ọ̀òjọ́, kí ó gbin iṣu kí ó ta ní ọ̀òjọ́, kí ó sì bá ewúrẹ́ ìbẹ̀rù jà; kò sí èyí tí kò kà á láyà nínú ìdánwò wọ̀nyí ṣùgbọ́n ìyá rẹ̀ ti ó ti di olóògbé yọ sí i, ó sì tán ìṣòro rẹ̀. Inú àlọ́ ni òkú ti máa ń padà di alààyè tí yóò sì ṣe nǹkan ìyanu. Bákan náà ni Ògòǹgò baba ẹyẹ tíí ṣe olórí àwọn ẹyẹ fi ojú Àkàrà-oògùn àti àwọn ògbójú ọdẹ yòókù han èèmọ̀ nínú ìrìnàjò wọn sí Òkè Láńgbòdó (nínú *Ògbójú)*. Ìyọnu tí Olówóaiyé ọmọ Akọ̀wédìran àti àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ rí láàfin Òjòlá-ìbínú tíí ṣe olórí ejò ayé gbogbo pẹ̀lú kò ṣe fẹnu sọ (*Igbó*).

Kókó mìíràn tí àlọ́ máa ń ṣàfihàn rẹ̀ ni ìdí abájọ. Àlọ́ yóò sọ ohun tó ṣe igún tó fi pá lórí àti ọ̀ran to ṣe àkàlà tó fi yọ gẹ̀gẹ̀ lọ́rùn. Bí orí ọ̀bọ ṣe pá, tí ìdí rẹ̀ sì hùrù, ohun tí ó ń mú àkókó máa fi ẹnu sọ igi kiri, tí ológbò àti èkúté sí di ata òun ojú, abbl. ni àlọ́ yóò sọ húlẹ̀húlẹ̀ rẹ̀. Àbùdá ìwà àlọ́ yìí náà kìí gbẹ́yìn nínú ìwé Fágúnwà. Nínú *Ògbójú* bí àpẹẹrẹ, a rí àlàyé nípa ohun tí ó mú ikú jẹ́ dandan fún àwa ọmọ adáríhunrun. Ìdí abájọ yìí náà, gẹ́gẹ́ bí Fágúnwà ṣe fi hàn, kò ju pé láti ìgbà tí a bá ti bí ọmọ ni àwọn màláíkà òde ọ̀run yóò ti gbé ẹ̀wù ikú wọ̀ ọ́ ní òdè ọ̀run kí ó tó mú ìrìnàjò rẹ̀ pọ̀n sí òde ìsálayé. Èyí náà ni ó sì fà á tó fi jẹ pé bí ó ti wù kí á pẹ́ tó láyé, àkùkọ gbọdọ̀ kọ lẹ́yìn ọmọkùnrin ní ọjọ́ kan. Nínú ìwé yìí kan náà ni a ti rí ìdí bí ewúrẹ́ ṣe di ẹran ọ̀sìn ní ilé.

Bí a bá wò ó, láti ìgbà dé ìgbà ni Fágúnwà ti máa ń ṣe àyàbá, àyàbá yìí sì le jẹ́ ti ìwàásù. Gbogbo ìwàásù Fágúnwà kì í dá lórí kókó ọ̀rọ̀ mìíràn ju òtítọ́, ìforítì, ìtẹpámọ́ṣẹ́, ojú kòkòrò, ìbínú, abbl. gẹ́gẹ́ bí ó ṣe máa ń wà nínú àlọ́. Àlọ́ yóò yòǹbó ìwà rere, yóò káràmásìkí ìwà ọmọlúwàbí, òtítọ́, inú rere, ìfẹ́, òdodo àti ìrànlọ́wọ́; yóò bu ẹnu àtẹ́ lu olè jíjà àti ìpànìyàn, yóò sì tẹ́ńbẹ́lú irọ́ pípa, ìgbéraga, rìkíṣí, ìṣọ̀tẹ̀, owú jíjẹ, tẹ̀mbẹ̀lẹ̀kun àti àwọn ìwà wọ̀nọ̀nnì tí ó tako òfin Ọlọ́run. Irúfẹ́ ẹ̀kọ́ wọnyí ni àlọ́ máa ń dá lé lórí, bẹ́ẹ̀ gan-an náà ni ó sì ṣe rí nínú àwọn ìwé Fágúnwà. Ṣé láárìjà àlọ́ ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìwà àti kíkọ́ ọmọ ní èdè, bẹ́ẹ̀ gẹ́lẹ́ ni àfojúsùn Fágúnwà rí. Olúborí ète rẹ̀ ni ṣíṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́, kì í sì í kẹ̀rẹ̀ láti ṣe èyí bí àǹfààní rẹ̀ bá ti ṣí sílẹ̀. Fágúnwà ni ó dúró bí apàálọ́ nígbà tí àwọn ogunlọ́gọ̀ òǹkàwé rẹ̀ jẹ́ olùgbọ́.

Ṣé ohun tí ó bá jọhun ni a fí í wé ohun, èèpo ẹ̀pà jọ pósí ẹ̀lírí, adígbónnákú jọ imí ahun; ìjọra tí ó ga jù lọ tí a tilẹ̀ lè tọ́kasí pẹ̀lú ìwé Fágúnwà ni ìhun tàbí àgbékalẹ̀ àlọ́ onítàn. Ìsọ̀rí mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ ni a lè pín àlọ́ sí ní eréfẹ̀ẹ́. Ìwọ̀nyí ni ìbẹ̀rẹ̀, ààrin àti ìparí. Apàálọ́ a máa ṣe ìfáàrà ní ìbẹ̀rẹ̀, lẹ́yìn èyí tí yóò sì na ẹnu mú ìtàn rẹ̀ sọ kí ó tó wá ṣe àlàyé orísìí ẹ̀kọ́ tí irú àlọ́ bẹ́ẹ̀ kọ́ wa ní ìparí. Fágúnwà a máa to ara rẹ̀ sí ipò asọ̀tàn, a sì máa ṣíde ìtàn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àpàálọ́ ti í ṣe fún àwọn olùgbọ́ rẹ̀. Èyí a máa jẹyọ nínú àwọn ìpèdè rẹ̀ bí "Ẹnyin ọ̀rẹ́ mi" (*Igbó)* àti (*Ìrèké)*, "Ẹnyin ọmọ enia" (*Ìrìnkèrindò*). Nínú ìfáàrà

rẹ̀ ni ó ti máa ń ṣe àfihàn asọ̀tàn lẹ́yìn èyí ni yóò sì mú kí ìpàdé wáyé láàrin asọ̀tàn àti òun fúnrarẹ̀ (Fágúnwà). Asọ̀tàn yìí le jẹ́ ọdẹ akíkanjú tí ó ń sọ ìtàn ara rẹ̀ (*Ògbójú*) tàbí kí ó máa sọ ìtàn ti baba rẹ̀ tí ó jẹ́ alágbára (*Igbó*). Ó tilẹ̀ le jẹ́ ọkùnrin lásán tí òǹkọ̀wé kò náání (*Ìrèké*). Irú ìtàn wọ̀nyí a máa ṣìde gẹ́gẹ́ bí ìtàn ìgbésí ayé akọni kan tí o mú ìrìnajò yìí pọ̀n fún ìdí kan tàbí òmíràn, nínú ìrìnàjò yìí ni yóò ti máa ti orí ìyọnu àti ìṣòro kàn bọ́ sí òmíràn nípa pípàdé oríṣìí abàmì ẹ̀dá, kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀; ìtàn náà á sì tí orí ìṣẹ̀lẹ̀ ojú ayé bọ́ sí ti méèríyìírí. Nínú *Ìrèké*, a rí òǹkọ̀wé tí ó ń ṣàlàyé bí òun àti àbúrò rẹ̀ ti ṣe ń lọ sí oko àti bí odò ṣe kún èyí tí ó mú kí ó dá àbúrò rẹ̀ padà sílé tí òun sì wẹ̀ kọjá odò àmọ́ sí ìyàlẹ́nu, ẹ̀dá kúkúrú kan olójú kan ni ó bá ní ìhà kejì odò yìí. Lẹ́hìn èyí ni irú àwọn ẹ̀dá abàmì báwọ̀nyí méje mú un ní ìgbèkùn. Báyìí ni ìtàn yìí bẹ̀rẹ̀ sí fẹjú síi pẹ̀lú ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìṣẹ̀lẹ̀ kàyééfì, kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀, ìtàn tí ó bẹ̀rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìṣẹ̀lẹ̀ ojú ayé di ti méèríyìírí.

Mélòó ni a ó kà nínú eyín adípèlé ni ọ̀rọ̀ Fágúnwà àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àràmọ̀ǹdà inú ìtàn rẹ̀, kò sí ọ̀kan nínú àwọn ìtàn rẹ máràárùn tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àràmọ̀ǹdà kò kún fọ́fọ́. Kódà ìṣẹ̀lẹ̀ wọ̀nyì ni ó fi ń ṣe òpómúléró ìtàn rẹ̀ torí bí a bá yọ wọ́n kúrò nínú ìtàn kọ̀ọ̀kan nǹkan yóò tán nílẹ̀. Nínú *Ògbójú,* Àkàrà-oògùn ṣe alábàápàdé oríṣìí ẹ̀dá ìbẹ̀rù bí Ẹbọra inú awùsá, Àgbákò, Kúrémbéte àti Tẹ̀mbẹ̀lẹ̀kun. Òun àti àwọn akọni yòókù ṣe àbápàdé Ẹ̀rù, Ògòǹgò fi ojú wọn rí àtàláátà baba àlàrùba níbi tí wọ́n ti kan èèmọ̀ lọ́wọ́ ẹranko ńlá, àwọn Iwin ilẹ àti Wèrè ọ̀run. Gbogbo àwọn ẹ̀dá wọ̀nyì ni ó ní àbùdá ìyanu. Àgbákò ní ojú mẹ́rìndínlógún, Kúrémbéte jẹ̀ iwin burúkú tí ó ní orí méjì àti ìwo méjì pẹ̀lú ojú ńlá kan ní ìgbá àyà rẹ̀, ṣẹyẹṣènìyàn ni Ògòǹgò torí pé orí ènìyàn ni ó ní, àwọn iwin ilẹ̀ pọ̀ bí bàbà èsùá, Wèrè ọ̀run sì búrú bí èṣù. Inú àlọ́ ni a ti máa ń bá oríṣìí nǹkan àràmọ̀ǹdà báwọ̀nyí pàdé èyí tí a máa ń lò láti le mú ìyanu bá àwọn ọmọdé kí ẹ̀kọ́ ìtàn náà sì le dúró ṣinṣin ní oókan àyà wọn. Ìṣẹ̀lẹ̀ ìjọjú yìí kò pin sí inú *Ògbójú* nìkan, ó tilẹ̀ kàmọ̀mọ̀ nínú *Igbó Olódùmarè*. Olówóaiyé ṣe àbápàdé Èṣú kékeré òde ní Aginjù Ìdákẹ́rọ́rọ́. Ẹ̀dá burúkú ni ẹbọra yìí, inú ọ̀gán ni ó sì ń gbé. Bí Olówóaiyé ti sọ, "ẹbọra kúkúrú bìlísì ni, ó máa ń gbé ẹrù pàsán kiri títí aiyé gbogbo" (o.i.12). Apejuwe ti Olówóaiyé ṣe nípa ẹbora yìí lásán tilẹ̀ to láti pa ojo kú kí ó sì mú alágbára máa tọ̀ sí ṣòkòtò. Yàtọ̀ fún Èṣù Kékeré Òde, ọdẹ aperin tún wọ̀yá ìjà pẹ̀lú Àǹjọ̀nnú Ìbẹ̀rù tíí ṣe Oníbodè Igbó Olódùmarè, ojú rẹ̀ rí màbo lori igi tí ó há sí kí Ọlọ́run tó yọ ọ́, bákan náà ni ó sì kó sínú pàkuté Òjòlá-ìbínú tíí ṣe olórí ejò ayé gbogbo.

Ìrèké Oníbùdò ní tirẹ̀ bá Ewúrẹ̀ ìbẹ̀rù jà, ó pa Ejò apanirun tí ó fẹ́ gbé Ìfẹ́pàdé mì, ikun imú ọ̀tún rẹ̀ sì bọ́ sí ti òsì kí òun àti àwọn ènìyàn rẹ̀ tó gun Òkè Hílàhílo dé òkè. Ẹlẹ́gbára ṣe ṣìá fún Ìrìnkèrindò, wọ́n ṣe alábàápàdé Ìgbéraga-Ìbànújẹ̀ àti Ahọ́ndiwúrà aya rẹ̀, ojú wọn sì rí tó kí wọ́n tó ká èso igi ìrònú. Àdìtú pàápàá kò ṣàlài fojú winá ní ìlú ìfẹ̀hìntì lẹyìn tí ó sì jàjàbọ́ tán, bí ó ti ń bá ejò jà ni o ń bá ọ̀ni jà, ojú rẹ̀ rí ìpọ́njú débi pé àìlẹ́nìkan jẹ́ kí ó pe ajá ni àwé nípa sísọ ẹranko di ọ̀rẹ́. Fágúnwà gan an alára tilẹ̀ jẹ́rìí sí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àràmọ̀ǹda àti ohun kàyééfì wọ̀nyí nígbà tí ó ń ṣàpèjúwe Igbó Olódùmarè. Ó ni.

> Ibẹ ni àwọn ẹiyẹ ti nfọhun enia, ti àwọn ẹranko nta ọja fun ara wọn, ti ogunlọgọ igi ko ni gbongbo sibẹsibẹ ti ara wọn tutu nini ti ewe wọn si dudu mirinmirin. Ekute tobi ju okete, igbin si tobi ju ijapa, ninu Igbo Olodumare. Awọn ẹbọra alagbara ati awọn jagidijagan anjọnnu ni nwọn si njumọ ṣe are pọ bẹni awọn ejo alakọri gbogbo a tun ma dẹruba awọn ọdẹ nitori ibẹ ni ile olori ejo aiye gbogbo, ojola-ibinu ni orukọ rẹ njẹ.
>
> (o.i. 8-9).

Ǹjẹ́ àlàyé òǹkọ̀wé yìí fúnra rẹ̀ kò ti kógojá pé ìṣẹ̀lẹ̀ abàmì ni ó kún inú àwọn ìwé ìtàn rẹ̀ fọ́fọ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ti máa ń rí nínú àlọ́?

Lẹ́yìn tí Fágúnwà bá ti ná ìgbárá ná ìgboro tán báyìí nínú ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìtàn rẹ̀ ni yóò wá mú iṣẹ́ wá sí ìparí. Ní ìparí yìí ni ó ti máa ń fi ẹnu ọ̀rọ̀ rẹ̀ jóná tí yóò sì gba òǹkàwé ní ìyànjú lórí kókó tí ó jẹ́ olúborí tí ó fẹ́ kí ó dìmú. A máa fi yé òǹkàwé pé kò sí ẹ̀dá kan tí kò ní la làásìgbò kọjá nínú ayé torí ojú tí kò rí pípọ́n iná, tí kò rí rẹ̀rẹ̀ oòrùn kò lè rí ohun tó ń dán yinrin bí idẹ, torí náà kí gbogbo mùtúmùwà sinmẹ̀dọ̀. Ó là á mọ́lẹ̀ nínú *Ògbójú* pé kò sí ẹni tí kò ní Òkè Láṅgbòdó tirẹ̀ láti lọ. Báyìí náà ni ó ṣe mú ọ̀rọ̀ rẹ̀ wá sí òpin nínú *Igbó Olódùmarè*.

> Mo fẹ ki gbogbo enia fi i si ọkan pe ko si ẹniti ko ni Igbo Olodumare tirẹ lati lọ ninu aiye, Igbo Olodumare ti ẹnikan yatọ si ti ẹnikeji ki Olodumare jẹki olukuluku ti Igbo Olodumare tirẹ de laini ipalara. Iṣoro ti a ko lagbara gbe ki Ọlọrun Ọba maṣe gbe e ka wa laiya. (o.i.163).

Ṣé ète Fágúnwà ni láti kọ́ àwọn òǹkàwe rẹ̀ lọ́gbọ́n, a kúkú máa tẹ̀ èyí mọ́ wọn létí ní ìparí ìtàn rẹ̀ kí ẹ̀kọ́ wọ̀nyí lè dúró ṣinṣin lọ́kàn wọn. Èyí kò sì yapa sì ìlàna àlọ́ náà níbi tí apààlọ́ ti máa ń fa kòmóòkun ọ̀rọ́ rẹ̀ yọ fún àwọn olùgbọ́ rẹ̀ ní ìparí àlọ́ rẹ̀. Bámgbóṣé (1974:9) náà jẹ̀rí sí èyí.

> The moral intention that runs through Fágúnwà's novels is perharps the most important single element in them. The author sees himself as someone who must teach and impart moral lessons, and his readers are expected to take these lessons to heart and learn from the incidents in the novels.

Bí Fágúnwà ti ń fi oríìṣí ìṣẹ̀lẹ̀, yálà nínú ojúlówó òpó ìtàn rẹ̀ tàbí àyàbá, kọ́ni ní ẹ̀kọ́ náà ni ó ti ipasẹ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ tí ó gba inú aginjù kan kọ́ni lọ́gbọ́n. Ọ̀pọ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ ni ó dúró gẹ́gẹ́ bí ibùdó ẹ̀kọ́. Àpẹẹrẹ ẹ̀dá wọ̀nyí ni: Àgùtan ìnàkí, Ìbànújẹ́ ìsàlẹ̀, Bàbá Onírugbọ̀n yẹ́úkẹ́ (*Igbo*), Gọ̀ṅgọ̀sú-tàkìtì, Aíyédèrú-ẹ̀dá, Ìbẹ̀m̀bẹ́-ọlọ́kùnrùn, Ìgbín ènìà, Ìfẹ́pàtàkì, Òmùgọ̀dìmeji, Òmùgọ̀dìmẹ́ta, Ìtándìran (*Ìrìnkèrindò*). Òǹkọ̀wé ti ipasẹ̀ àwọn ẹ̀da ìtàn rẹ̀ kọ́ni ní oríṣìí ẹ̀kọ́. Irele (1975) tún tọ́ka sí èyí.

> The significance of his work is thus inherent in the symbolic framework and connotations of his novels. A simple but valid interpretation of the pattern of situation in his novels suggests that his forest stands for the universe, inhabited by obscure forces to which man stands in a dynamic morals and spiritual relationship and with which his destiny is involved. (p. 81-82)
>
> Lááríjà iṣẹ́ rẹ̀ hànde nínú àgbékalẹ̀ àti ìjásí àwọn ìtàn rẹ̀. Ìtumọ̀ tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn rẹ̀ ní, tí kò ṣe é jà níyàn, ni pé aginjù rẹ̀ dúró fún ilé ayé nínú èyí tí onírúurú àti oníwàáwà ènìyàn ń gbé tí wọn sì jọ ń ní ìfarakínra nínú ara àti ẹ̀mí lórí èyí tí àyànmọ́ wọn dá lé.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Ní àìṣe àníàní, Fágúnwà gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé ń fi iṣẹ́ ọnà rẹ̀ ya àwòrán àwùjọ rẹ̀ síta kedere fún ayé rí yálà fún ìyọ̀nbo, ìkan-sáárá-sí, ìbu-ẹnu-àtẹ́-lù, fún ìbáwí, tàbí fún àtúnṣe. Gbogbo ìlàkàkà òǹkọ̀wé ni láti mú àyípadà tó dára bá àwùjọ rẹ̀ kí ìgbáyégbádùn le wà, kí ìdàgbàsókè sì le tó àwùjọ lọ́wọ́. Nípasẹ̀ síṣe èyí ni lítíréṣọ ṣe lè ṣe ojúṣe rẹ̀ kí ó sì jẹ́ olótìítọ́ sí àwùjọ rẹ̀. Ernest Fischer fi ara mọ́ èrò wa yìí pé bí owó-orí ṣe jẹ́ dandan, tí aṣọ ìbora sì jẹ́ túláàsì, ni ó pọndandan fún lítíréṣọ láti jẹ́ olótìítọ́ nípa jíjẹ́ iṣẹ́ fún àwùjọ rẹ̀. Àkàngbé (2005:28) ṣe àmúlò láti inú iṣẹ́ Fischer pé,

> In a decaying society, art, if it is truthful, must also reflect decay. And unless it wants to break tradition with its social function, it must show the world as changeable, and helps to change it.
>
> Bí iṣẹ́ ọnà yóò bá ṣe olóòótọ, ó gbọ́dọ̀ ṣe àfihàn àwùjọ tí ó ń jẹrà gẹ́gẹ́ bí èyí tí ó ń díbàjẹ́. Bí kò bá ní tàpá sí ojúṣe rẹ̀ sí àwùjọ, ó gbọ̀dọ̀ ṣàfihàn ayé gẹ́gẹ́ bí èyí tí ó ṣe é yípadà, kí ó sì sa apá láti yí i padà.

Nítorí náà, ó di dandan kí iṣẹ́ ọnà ṣe àfihàn àwùjọ gẹ́lẹ́ bí ó bá ti rí. Ṣé bí ojú bá ń ṣe ipin, a máa ń yọ ọ́ han ojú ni pé ó ń ṣe àìdára. Bi àwùjọ bá ń díbàjẹ́, iṣẹ́ ọnà gbọ́dọ̀ fi ìdíbàjẹ́ rẹ̀ hàn; bí ó bá sì ń tùbà-tùṣẹ, tí ó sì péye, iṣẹ́ ọnà gbọ́dọ̀ fi ìpéye àti ìkún-ojú-ọ̀ṣùwọ̀n rẹ̀ hàn bákan náà gẹ́gẹ́.

## Ìyapa Iṣẹ́ Fágúnwà sí Àlọ̀

Pẹ̀lú atótónu wọ̀nyi, a ti fi ìdí èro wa múlẹ̀ pé ìjọra tí ń bẹ láàrin àlọ́ ati iṣẹ́ Fágúnwà kìí ṣe kèrémì. Ní òtítọ́ ni èyí rí bẹ́ẹ̀, àmọ́ a kò le ṣaláí rí àwọn ìyapa kọ̀ọ̀kan tọ́ka sí. Iyapa tí ó hànde jù **sí** àlọ́ ni ọgbọ́n àyàbá tàbí fitànsọ̀tàn tí Fágúnwà lò. Èyí ni ṣíṣe àmúlò ìtàn nínú ìtàn láti le mú kí ìtàn fẹjú. Ìlò àyàbá báwọ̀nyí a máa fún òǹkọ̀wé ní àǹfààní láti ṣe àfikún tí ó bá ní lọ́kàn àmọ̀ tí ó nira fún un láti gbé wọ inú ojúlówó ìtàn. Ìlò àyàbá yìí jẹ Fágúnwà lógún torí pé àwọn ni ó so iṣẹ́ rẹ̀ ró. Ọgbọ́n àyàbá yìí a máa fún Fágúnwà ní àǹfààní láti ṣe ìwàásù, kí ó sì sọ ìtàn orísìírìṣìí pẹ̀lú ṣùgbọ́n àjèjì ni ìlò àyàbá jẹ́ sí àlọ́. Àlọ́ a máa ní òpó ìtàn tí ó gún tí ó sì lọ tààrà. Àlọ́ kìí yà sígbó yà síjù; sàn-an làá rìn ni ọ̀rọ̀ tirẹ̀ àmọ́ èyí kò rí bẹ́ẹ̀ nínú àwọn ìtàn àròsọ Fágúnwà nínú èyí tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àyàbá wà. Ète ìlò àyàbá wọ̀nyí ni láti lè jẹ́ kí ìtàn rẹ̀ kún.

Èdè tún jẹ́ orísun ìyapa iṣẹ́ Fágúnwà mìíràn sí àlọ́. Èdè geere, èdè sàn-an, èdè ọmọdé pẹ̀lú ni ti àlọ́. Ṣé ìka tí ó bá tọ́ sí imú ni a fi í re é, èdè tí ó tọ́ sí àwọn ọmọdé tí a máa ń fi àlọ́ kọ́ lọ́gbọ́n náà ni a máa ń lò. Ṣé àlọ́ ni tọmọdé òwe ni tàwọn àgbà, a kò lè ṣe àmúlò èdè tí ó ki fún àlọ́ torí kí ó le yé àwọn olùgbọ́. Torí náà, èdè sánpọ́nná ni ti àlọ́ ṣugbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ nínú ìwé Fágúnwà. Èdè Fágúnwà kì í ṣe èdè èwe tàbí ti ọ̀gbẹ̀ri rárá, èdè rẹ̀ kún, ó ki, ó sì lóyin pẹ̀lú. Èdè rẹ̀ kì í ṣe èdè arọ̀bó tàbí àwọ̀ṣe, èdè abílọ́jẹ̀ tí o mọ awo í ṣe ni.

Ṣe àìsọ̀rọ̀yánrọ̀ ni ó pa Elénpe ìṣaájú, bí a bá rí ọ̀nà kan tàbí méjì tí iṣẹ́ Fágúnwà fi yàtọ̀ sí àlọ́, àmọ́ nìyẹn kò mọ́ ara ẹran. Ìdí ni pé Fágúnwà kì í kúkú ṣe apàálọ́ tàbí asọ̀tàn. Òǹkọ̀wé lítíréṣọ̀ alátinúdá Yorùbá ni. Iṣẹ́ lítíréṣọ̀ sì pè fún àtinúdá, àrògún, ìpaláró àti àsọdùn. Ọtun ọ̀tun ni ọjọ́ọ́ yọ, ọ̀tun ọ̀tun ni òòrun í ràn, ọ̀tun ọ̀tun náà ni ìrònú onísẹ́ ọ̀nà lítíréṣọ̀. Iṣẹ́ lítíréṣọ̀ gbọ́dọ̀ rẹwà, kí ó tó di pé ó yege, òǹkọ̀wé kò sì gbọ́dọ̀ káàárẹ̀ láti pèsè èròjà ẹwà wọ̀nyí; àìjẹ́ bẹ́ẹ̀, awo rẹ̀ yóò sùn ní ebi. Oríṣìríṣì ọ̀nà ni ẹwà le



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

gbà wáyé. Ẹwà le wáyé láti ipasẹ̀ èdè, àgbékalẹ̀ ìtàn, ẹ̀da ìtàn àti kókó ìtàn pẹ̀lú. Fágúnwà mọ ìdí abájọ wọ̀nyí kò sì káàárẹ̀ láti ṣe àmúlò wọn bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ. Ó mọ iṣin jẹ, ó sì mọ ikú ojú rẹ̀ yàn. Ìdí nìyí tí a fi sọ pé ó kàn ṣe àmúlò bátànì àlọ́ kí iṣẹ́ rẹ̀ le múnádóko ni, kìí ṣe pé ó kúkú ń pa àlọ́, a kò sì gbọdọ̀ retí kí iṣẹ́ rẹ̀ jẹ́ àlọ́ gẹ́lẹ́.

**Àgbálọgbábọ̀**

Ní àkótán, kò yẹ kí á kádìí ọ̀rọ̀ láìgbé ọ̀ṣùbà ẹ̀yẹ fún Fágúnwà. Yàtọ̀ sí pé ó fi àpẹẹrẹ iṣẹ́ àṣeyọrí lélẹ̀ gẹ́gẹ́ bí akọni òǹkọ̀wé, àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí kún fún ìwàásù àti ìmọ̀ràn tí ó lè mú ọ̀nà ọmọ ẹ̀dá gún kí ayé rẹ̀ sì tòrò. Bóyá ni a sì lè rí òmíràn nínú ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá tí ó ṣe àkópọ̀ àìmọye ẹ̀kọ́ gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú àwọn ìwé Fágúnwà.

**Ìwe Ìtọ́kasí**


Abimbola, W. (1965). "Yoruba Oral Literature", *African Notes*, Vol. 2, Nos. 2-3, pp. 1 - 4.

Adejumo, A. (2011). "Text and Inter-textuality in contemporary Yoruba Literary works" in Falola and Oyebade (eds.). *Yoruba Fiction, Orature, and Culture.* Trenton: Africa World Press.

Akangbe C.A. (2005). "From the Stage to Motion Pictures: The Changing Phases of Lérè Pàímọ́ Theatre." An Unpublished Master of Arts Project in the Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Ibadan.

Adélékè, D. (2011). *Lẹ́yìn Ìtàn Àròsọ Fágúnwà Máràárún, Èwo ló kù?* Ibadan: DB Martoy Books.

Àlàbá A. àti Ògúnṣípẹ̀ (1982). *Ìwé afinimọ̀nà lórí àwọn Ìwé Fágúnwà.* Ikeja: Thomas Nelson (Nigeria) Ltd.

Bamgbose, A. (1974). *The Novels of D.O. Fágúnwà.* Benin-City: Ethiope Publishing Corporation.

Fágúnwà, D.O. (1938). *Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmalẹ̀.* Ikeja: Thomas Nelson and Sons Ltd.

Fágúnwà D.O. (1949). *Igbó Olódùmarè.* Ikeja: Thomas Nelson and Sons Ltd.

Fágúnwà, D.O. (1949). *Ìrèké Oníbùdó.* Ikeja: Thomas Nelson and Sons Ltd.

Fágúnwà D.O. (1954). *Ìrìnkèrindò Nínú Igbó Elégbèje.* Ikeja: Thomas Nelson and Sons Ltd.

Fágúnwà D.O. (1961). *Àdììtú Olódùmarè.* Ikeja: Thomas Nelson and Sons Ltd.

Haberer, A. (2007). *Intertextuality in Theory and Practice.* Literatura 49(5).

Humanities.wisc.edu/assets/misc/what_is_intertextuality.pdf. Accessed Thursday 28th July, 2016.

Irele, A. (1975). "Tradition and the Yoruba Writer: D.O. Fágúnwà, Amos Tutuola and Wole Soyinka" in *Odu-A Journal of West African Studies*, University of Ife, New series, No 11.

Kristeva, J. (1966). *The Kristeva Reader.* Torill Moi (ed.). Oxford: Blackwe.

Kristeva, J. (1967). "Bakhtine, le mot, le dialogue et le roman." Paris: *Critique*, (33,239) 438 – 465.

Ògúndèjì, P.A. (1991). *Ìfáárà sí Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá.* Ibadan: Ibadan External Studies Programme.

Olatunji, O. (1984). *Features of Yoruba Oral Poetry.* Ibadan: University Press Ltd.




UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Olunlade, T.A. (1999). "Àgbéyẹ̀wò Èèwọ̀ Nínú Àṣàyàn Oríkì àti Orílẹ̀ Yorùbá", *Unpublished M.A. Thesis*, Dept of African Languages and Literatures, Obafemi Awolowo Universitiy, Ile-Ife.
Ọpádọ̀tun, O. (1994). *Àsàyàn Àlọ́ Onítàn.* Ibadan: Y-Books.
Soyinka, W. (1976): *Myth, Literature and the African World.* Cambridge University Press, Cambridge.
Taiwo, O. (1967): *An Introduction to West African Literature.* London: Oxford University Press.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY